# BÀBÁ ÌJẸ̀BÚ, ALÀGBÀ JÓSẸ́FÙ RÓTÌMÍ ADÉBÁMBỌ̀

**By**

**Bọ́láńlé Aya Ọ̀ṣọbà**

**Department of Nigerian Languages,**

**College of Languages and Communication Arts Education.**

**Lagos State University of Education, Oto/Ijanikin Lagos with Campus at Epe.**

**DOI:** https://doi.org/10.5281/zenodo.8324929

**Orin**: Má á bá Jẹ̀bú relé ọmọ aláré… (2ce)

Isẹ́ ni òògùn ìṣẹ́
Múra sísẹ́ ọ̀rẹ́ ẹ mi
Iṣẹ́ ni a fi ń dẹni gíga
Alàgbà Adébámbọ̀ ti múra síṣẹ́,
Wọ́n ti se gudugudu méje

Wọ́n ti se yààyà mẹ́fà
Alàgbà Adébámbọ̀ ti ṣiṣẹ́ nínú ọgbà 'AOCOED' àti 'LASUED' fún odindi ọdún méjìlélọ́gbọ̀n gbáko
Alàgbà Adébámbọ̀ ti gbéyán fẹ́gbẹ́, wọ́n sì gbàwo bọ̀

Opẹ́ f'Élédùà fún oore ńlá tí ó ṣe
Alàgbà Adébámbọ̀ Jẹ́jẹ́nìwà ló fẹ́ fiṣẹ́ sílẹ̀
Iṣẹ́ kò fi ẹ̀gbọ́n wa sílẹ̀

Ọpẹ́ ńlá f'Élédùà fún oore ńlá yìí
Ọ̀kẹ́ àwọn ènìyàn lè jọ gbaṣẹ́ lásìkò náà
Ṣùgbọ́n tí iṣẹ́ tí fẹyìn wọn tì.
Ọ̀pọ̀ ló ti gbẹ́mì ín mì
Ọ̀pọ̀ ló wà ni dùbúlẹ̀ àìsàn

Ọ̀pọ̀ sì ni ìjì líle ayé ti gbá wọn dànù lẹ́nu iṣẹ́
A kò fi èyí yọ̀ wọ́n

Ṣùgbọ́n a fi ń dúpẹ́ lọ́wọ́ Aláwùràbí
Fún oore ńlá tó ṣe ẹ̀yín ni
Lááárin ọdún méjìlélọ́gbọ̀n yìí
Iṣẹ́ tiyín kò gbé yín wọ wàhálà
Ẹ ò dẹni tí àwọn aláṣẹ ń pè sínú ìpàdé ìjẹ́jọ́
Láti wá ṣàlàyé ohun tí kówá rí lọ́bẹ̀

Tó fi waaro ọwọ́
A bá a yín yọ̀
A bá a yín dúpẹ́
Títí láéláé lọpẹ́ wa lọ́dọ̀ rẹ Elédùà
Títí láéláé la ó máa yòǹbó rẹ Alágbàwíẹ̀dá
Wí pé pẹ̀lú ayọ̀ àti ìdùnú àti ìlera pípé
Lẹ̀yín ń fẹ̀yìntì
Múso! Músò!! Músò! S'ọ́ba Òkè
Ọ̀pọ̀ akẹ́kọ̀ọ́ ló ti bùnmu nínú omi ọgbọ́n yín
Ọ̀pọ̀ akẹ́kọ̀ọ́, wọ́n ti dẹni ńlá lókè èèpẹ̀
Kò gbàgbé ọmọ Adébámbọ̀ Jẹ́jẹ́nìwà

Àwọn akẹ́kọ̀ọ́tí wọ́n ti di ìlú mọ̀ọ́ká
Kò le è gbàgbé ipa ribiribi tí ẹ kó
Nínú àti gòkè wọn
Ìfẹ́ ńlá lẹ fi ń bá mùtúmùwà ló
Alàgbà Jẹ́jẹ́nìwà, ti gbóúnjẹ fẹ́gbẹ́

Ẹ gbàwo bọ̀
Ẹ kógo já
Akínkanjú alákadá lẹ̀yin jẹ́
Láìwòwé, ọlọ́pọlọ pípé ínú Gírámà Yorùbá.
Àjò kò lèdùn
K'ónílé má relé

Ẹ̀yin ti lo ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún nílùú Èkó
Àkókò tó wàyìí láti ṣẹ́rí re'lé
Àjò kò lè dùn dùn dùn dùn,
Kó nílé má relé

Torí bó pẹ́, bóyá,
Onílé á re'lé
Bàbá Ìjẹ̀bú ń relé

Òwu Ìjẹ̀bú ni ilẹ̀ ẹ̀gbọ́n mi àtàtà
Níbi tí bàbá yóò ti má a jẹ
Ìkọ́kọrẹ́ láàárọ̀ àti Ẹ̀bẹ rìpò lálẹ́
Oúnjẹ Ìjẹ̀bú tó gbalé gbako
Tó ń ṣara lóore,
Tó sì ń mára dán
Tó mú ọpọlọ jí pépé
Àwa ti bẹ Elédùà

Láti fún-un yín ní ìsinmi aláyọ̀
Nítorí lẹ́yìn ìfẹ̀yìntì yìí
Ẹ̀yín ò ní rá'hùn ohunkóhun,
Agbe yóò gbére kò yín
Ẹ ó máa ríná, rí lò lọ́jọ́ gbogbo
Àṣeyọrí àti àṣeyege ni ohun gbogbo tí ẹ bá ń dáwọ́lé yóò jẹ̀ é
Ẹ̀gbọ́n àtàtà ni ẹ̀gbọ́n tí mo ní

Ẹ̀gbọ́n àtàtà ni ẹ̀gbọ́n Jẹ́jẹ́nìwà
Ẹ̀gbọ́n tó fẹ́ àbúrò dénú l'ẹ̀gbọ́n-ọ̀n mi.
Ẹ̀gbọ́n Adébambọ̀ Rótìmí jẹ́ ẹ̀gbọ́n rere
Ẹ̀gbọ́n tó nífẹ̀ẹ́ àbúrò dénúdénú
Ẹ̀gbọ́n tí kìí jẹ nídìí mọ̀dàrú

Ẹ̀gbọ́n tí ó máa ń dúró ti òótọ́

Ẹ̀gbọ́n tí ó máa ń gbèrò ohun
Rere sọ́mọnìkejì ní gbogbo ìgbà
Ọjọ́ ti pẹ́, ọjọ́ ti pẹ́ kánrinkése
Nígbà tí mo jẹ́ màjèsín nílé Ifẹ̀

Tí baba ẹ̀gbọ́n yìí tí ń ṣiṣẹ́ ajé
Iṣẹ́ ajé sọmọ nù bí òkò
Búrẹ́dì tí ó jẹ́ ti bàbá Adébámbọ̀
Ẹ̀yí tó fikalẹ̀ sádùgbóò Kóìíwò léti Akarabata
Ni Ifẹ̀ ooye laàgbò

Níbití ojúmọ́ ti ń mọ́ wá
Ẹni tí kò bá mọ búrẹ́dì yìí nílùú Ilé-ifẹ̀
Ó túmọ̀ sí wí pé kò gbélé Ifẹ̀ nù u
Búrẹ́dì tí tẹrútọmọ, tarúgbó-tọmọde
T'ọ̀tọ̀kùlú àti gbajúmọ̀ ń wáríí fun

Bàbá wa Ọ̀túnba Rúbẹ́nì Òkúnúgà Adébámbọ̀
Ní Ọlọ́run jogún irúfẹ́ búrẹ́dì yìí fún un
Tí wọn jẹ́ alákòóso
Ilé-iṣẹ́ búrẹ́dì yìí bẹ̀rẹ̀ láti ọdún 1956-1995
Òhun nìkan ni ilé-iṣẹ́ búrẹ́dì jákèjádò ni
Gbogbo Ilé-Ifẹ̀ àti ìgbèríko tí ó ní
Irinṣẹ́ búrẹ́dì ìgbàlódé
Irinṣẹ́ tí ń lo búrẹ́dì, tí ó sì ń gé e
Fún gbogbo akitiyan baba
Gẹ́gẹ́ bí ẹni tí Ọlọ́run dá lọ́lá

Tíṣẹ́ búrẹ́dì yìí jẹ iṣẹ́ àṣejèrè fún wọn
Gbogbo àwọn oníbúrẹ́dì ní ìwọ̀ oòrùn
Fí oyè ńlá dá baba lọ́lá
Wọ́n fi wọn ṣe alága fún gbogbo
Oníbúrẹ́dì ní ìpínlẹ̀ Iwọ̀ Oòrùn
Tolórí tẹlẹ́mù ni ó ń gbádùn búrẹ́dì baba

Bí àwọn ti Yunifásitì Ilé-Ifẹ̀ tí ń
Gbádùn rẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọba
Aláyé bi Adésọjí Adérẹ̀mí, Ọ̀ọ̀ni Ilé-Ifẹ̀
Ọba tí ó gbayì títí di ọjọ́ ikú
Ń yòǹbo búrẹ́dì ti ilé-iṣẹ́ Adébámbọ̀

Àwọn oníbúrẹ́dì ni Làgèrè, Mọ̀ọ̀rẹ̀
Ìrẹ́mọ, Ọ̀jọ̀yin nílé Ifẹ̀,
Gbogbo ìpàdé di Kóìíwò ni ilé-iṣẹ́ Bámbọ̀
Alàgbà Adébámbọ̀ ń lẹ ọmọ Òwu Ìkijà ní ìpínlẹ̀ Ògùn
Ọkọ Ọlájùmọ̀ké, ìwọ ni mó ń ké sí

Ọkùnrin kúkúrú àbìjà kunkun
Ọjọ́ pẹ́, ọjọ́ pẹ́ kánrinkése
Ní nǹkan bi ọdún mọ́kàndínlógún sẹ́yìn
Ni mo ṣàlábàápàdé Alàgbà Adébámbọ̀
Ní ẹ̀ka ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá ní ìlú Ìjànikin

Wọ́n kí mi tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀, tìrẹ̀lẹ̀-tìrẹ̀lẹ̀
Wọ́n kí mi káàbọ̀ ságbolé akadá
Wọ́n gbàmí nímọ̀ràn lórí ọ̀nà àti ṣàṣeyọrí
Wọ́n mẹ́nùbàá lọ́jọ́ náà lórí ọ̀rọ̀
Àti gòkè nínú iṣẹ́ akadá
Wọ́n ṣàlàyé lórí pépà kíkọ láti gòkè
Ẹ̀gbọ́n àtàtà kọ oríṣìíríṣìí ìwé
Wọ́n fi ṣemi lóore níjọ́ à ń wí náà
Inúù mi dùn ọkàn mí yọ̀,
Mo délé wí pé mó rẹ́nifojújọ

Mo régbọ̀n-ọ́n àtàtà, ọmọ ojúlówó Ìjẹ̀bú
Ìmọ̀ràn yìí ràn-mí lọ́wọ́ púpọ̀púpọ̀
Mo ṣèlérí fún ọkàn mi pé
Ó di dandan kí ń mókè nínú

Iṣẹ́ akadá, Èdùmàrè sì gbàá bẹ́ẹ̀

Mo ki ẹ̀gbọ́n mi àtàtà, baba Dàmiláre
Ẹ̀gbọ́n tó nífẹ̀ẹ́ tẹrú tọmọ

Baba Ọrẹolúwa, Baba Ṣeun
Mo dúpẹ́ púpọ̀ fún ìmọ̀ràn ọjọ́sí
Mo dúpẹ́ wí pé Olúwa gba ògo
Alàgbà Adébámbọ̀ Rótìmí ǹ lẹ́
Ọmọ Ìjẹ̀bú Alárẹ̀, ọmọ Òwu Ikija

Kékeré Ìjẹ̀bú, owó ni
Àgbà Ìjẹ̀bú, owó ni
Ẹ̀wẹ̀ sóo, Ẹ̀ wẹ̀ sóo
Kin lẹ̀ ń ṣe lóko, tẹ fi dòru
Ọgànjọ́ lẹgan, ọmọ alárẹ̀, ẹ̀wẹ̀ só o

Ẹ̀wẹ̀ só o, Ẹ̀wẹ̀ só o, ọmọ alárẹ̀, ẹ̀ wẹ̀ só o
Ìṣe Ìjẹ̀bú ro alàgbàAdébámbọ̀ Jẹ́jẹ́nìwà
Alábájọ tí Alàgbà Adébámbọ̀ fi máa ń náwó bíi Ẹlẹ́dà
Ọ̀pọ̀ ènìyàn ló ti mọ̀yìn mọṣẹ rere
Ọ̀pọ̀ ènìyàn ló ń ṣe sàdáńkàtà

Fún ìwà akin, ìwà akinkanjú
Ti ẹ máa ń hù
Tẹrú-tọmọ ni ó máa ń dámúsò
Fún nawo-nawo tí ẹ máa ń ṣe
Alábájọ ti ọkọ Ọlájùmọ̀kẹ́ kìí rojú àti
náwó iyì lọ́jọ́kọ́jọ́
Gbogbo mùtúmùwà ló mọ̀ wí pé
Náwónáwó nìran Ìjẹ̀bú
Àwa Ìjẹ̀bú kì í ṣahun
Níbi tí ó bá yẹ láti náwó

Àwọn Ìjẹ̀bú a má a ṣe gudugudu méjè

Yààyà mẹ́fà
Ìṣe Ìjèbú yìí ro Ọ̀gbẹ́ni Jẹ́jẹ́nìwà púpọ̀.
Níbikíbi, nígbà gbogbo, ni wọ́n ti ń náwó lọ
Mo gbàdúrà wí pé ìná kò nítán owóo yín

Àgbàná kò ni wọ owó náà
Èrè lobìnrin í jẹ lábọ̀ ọjà
Láṣẹ Èdùmàrè, ẹ ó máa jèrè ni
Gbogbo ènìyàn pátá porogodo ló mọ̀ wí pé,
Ìwà rere lẹ̀ṣọ́ ènìyàn, ìwà ọmọ níí sii mú ọmọ jẹ́ òkígbẹ́
Ọkọ Ọlájùmọ̀kẹ́, má yíwà rere padà
Baba Ṣeun, Baba Dáre, Baba Ọrẹ-Olúwa
Máa ṣee rere nìṣó, láìpẹ́ láìjìnnà
Ìka yóò ka oníkà, rere á ba ẹni rere

Alàgbà Rótìmí Jóṣẹ́fù Adébámbọ̀ jẹ
Alárògún àti aláròjinlẹ̀ ẹ̀dá
Rere ló pé ìkà kò pé
Rere ni ká máa ṣe lọ́jọ́ gbogbo
Aláwùràbí yóò rántí oore gbogbo
Tí ẹ ti ṣe fún tẹrútọmọ
Yóò sì san yín lẹ́san rere
Ogún ọmọdé kò le è ṣeré f'ógún ọdún
Ó dùn wá jọjọ wí pé ẹ ń fi wá sílẹ̀ lọ
Ọba òkè yóò pẹ̀lú yín.

Mo rántí ní nǹkan bí oṣù méjì sẹ́yìn, tí a ṣè pàdé Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́
Gbogbo wa la b'omi lójú wẹ̀rẹ̀wẹ̀rẹ̀
Nítorí ifẹ́ ńlá tí a ní sí i yín jọjọ
Ó dùn wa jànjàn, ó dùn wá jànjàn wí pé ẹ ń lọ

Gbogbo wa ní Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ ń kí i yín pé ó dìgbòóṣe fún sáà kan ná

Ó dàbọ̀, ó dìgbòóṣe
K'Ọ́lọ́run ṣọ́ ìpàdé wa
Ká ríra pẹ̀lú ayọ̀
Ká má pẹ̀ẹ́ ríra wa
Bọ́láńlé aya Ọ̀ṣọbà, Tayé aya Kẹ́hìndé,

Ọpẹ́yẹmí aya Sánní, Níkẹ̀ẹ́ ayá Adékọ̀yà,
ń kí i yín pé, ó dìgbòóṣe
Kòfẹ́ṣọ̀ Àkànmú, Ọ̀gbẹ́ni Ṣólàjà àti Adégúnlẹ̀
ń kí ì yín pé ó dàbọ̀

A gbàdúrà wí pé
Ayọ̀ Ọlọ́run yóò má a bá a yín gbé.

Ìfẹ̀yìntì ayọ̀ nínú ọláńlá
Ìgbéga tó bùáyà
Ire kàbìtì lọ́ọ̀dẹ̀ gbogbo wa.
Ire o.

.